Ètò Ìlànà Ìwọ̀n Ìdíyelé owó Ìpele Gúùsù ìkínní (1):

# ÀWỌN ÌGBẸ́JỌ́ GBOGBOGBÒ

Maryland Transportation Authority MDTA

**American Legion Bridge I-270 to I-370**




Àṣẹ Ìgbòkègbodò-ọkọ̀ ìlú Maryland [Maryland Transportation Authority (MDTA)] ń́gba àwọn àsọyé gbogbogbò gẹ́gẹ́ bíi ìpín ètò ìlànà owó ìdíyelé fún Ìpele Gúùsù Ìkínní (1): Afárá Légíọ̀nù Amẹ́ríkà I-270 sí I-370. À ńṣe àwọn ìgbẹ́jọ́ gbogbogbò fún àwọn tí ó wà ní ojúkojú àti àwọn tí wọ́n pè wọlé láti sọ àsọyé lábẹ́ àṣẹ fún àkọsílẹ̀ nípasẹ̀ ọ̀rọ̀ tí a sọ ti gbogbogbò tàbí ní ẹ̀rí ẹnìkan sí ẹnìkan tàbí nípasẹ̀ àsọyé tí a kọ sílẹ̀.

Ẹ̀rí ìgbẹ́jọ́ gbogbogbò ojúkojú náà yóò wáyé ní ọjọ́ kejìlá (12) ní Ilé-ìtura Hilton Washington DC/Rockville & Executive Meeting Center ní Rockville, pẹ̀lú sáà méjì láti aago 2 sí 4 ọ̀sán àti láti aago 6 sí 8 àsálẹ́, èyítí ó ń́gbà ànfààní pípèsè ẹ̀rí nípa ọ̀rọ̀ tí àwùjọ àti ẹ̀rí ẹnìkan sí ẹnìkan láàyè (a gba ni níyànjú láti fi orúkọ sílẹ̀ ṣáájú). Gbogbo òṣìṣẹ́ MDTA àti àwọn olùkópa ní ìgbẹ́jọ́ ojúkojú náà yóò nílò láti tẹ̀lé ìtọ́nisọ́nà CDC tí ó níiṣe pẹ̀lú KOFID-19.

Ẹ̀rí ìgbẹ́jọ́ gbogbogbò  ti pípè wọlé ti ọjọ́ kẹ̀rìnlá (14) Oṣù keje náà yóò ní sáà méjì láti aago 2 sí 4 ọ̀sán àti láti aago 6 sí 8 àsálẹ́, èyítí ó ń́gbà ànfààní pípèsè ẹ̀rí nípa ọ̀rọ̀ tí àwùjọ nípasẹ̀ fóònù láàyè (fífi orúkọ sílẹ̀ ṣáájú  - nípasẹ̀ àyélujára tàbí fóònù bí a ṣe kíyèsi ní àlàfo búlù tí ó dúdú gan ní apá ọ̀tún lókè - ni a nílò láti gba ni láàyè sí títò wọlé fóònù). Láti pèsè ẹ̀rí nípa pípè wọlé, pe 855-701-1977 kí o sì fi ohùn tí a gbà sílẹ̀ kansoso èyítí kò jú ìṣẹ́jú mẹ́ta lọ sílẹ̀.

# Darapọ̀ mọ́ wa fún àwọn Ìgbẹ́jọ́ Gbogbogbò

Jọ̀wọ́ ṣe àtúnyẹ̀wò àwọn ohun-èlò àwọn ìgbẹ́jọ́ gbogbogbò ṣáájú kí o tó wá sí ìgbẹ́jọ́ gbogbogbò kan ní **mdta.maryland.gov/ALB270TollSetting**. Ojú òpó lórí ayélajára ní Yàrá Àlàyé lórí Ayélujára kan fún àfihàn àti àwọn àlàyé gbogbo ohun-èlò ìgbẹ́jọ́ náà nínú. Kò ní sí àgbékalẹ̀ ní àkókò àwọn ìgbẹ̀jọ́ gbogbogbò, tí a kò ní fi ààyè sílẹ̀ sí àwọn èsì sí àwọn ìbéèrè.

Gbogbo ènìyàn lè tẹ́tí sí ẹ̀rí ìgbẹ́jọ́ náà ní ojukojú bí ó ṣe ń́lọ lọ́wọ́ nípa pípe **855-701-1977** tàbí títẹ́sí sí èyítí à ń́fihàn bí ó ṣe ń́lọ lọ́wọ́ nípa bíbẹ **mdta.maryland.gov/ALB270TollSetting** wò.

## ẸRÍ ÌGBẸ́JỌ́ NÍ OJÚKOJÚ

**Ọjọ́ Ajé, ọjọ́ kejìlá (12) Oṣù keje (2-4 PM ÀTI 6-8 PM)**
Hilton Washington DC/Rockville Hotel & Executive Meeting Center
1750 Rockville Pike, Rockville, Maryland 20852
(a gba ni níyànjú láti fi orúkọ sílẹ̀ ṣáájú)

## PÍPÈ WỌLÉ SÍ ẸRÍ ÌGBẸ́JỌ́

**Ọjọ́ru, ọjọ́ kẹ̀rìnlá (14) Oṣù keje (2-4 PM ÀTI 6-8 PM)**
(nílò fífi orúkọ sílẹ̀ ṣáájú)

## FÍFI ORÚKỌ SÍLẸ̀ FÚN ÌGBẸ́JỌ́
**mdta.maryland.gov/ALV270TollSetting**
**tàbí 888-725-0174**

Ní àfikún sí àwọn ìgbẹ́jọ́ náà, àwọn àsọyé tí a kọ àti ìpè wọlé sí ẹ̀rí nípa ohùn tí a fi ráńṣẹ́ ni a ó gbà fún àkọsílẹ̀ lábẹ́ àṣẹ ní **Ọjọ́bọ̀, Ọjọ́ kejìlá (12), Oṣù kejọ, ni aago 5 PM:**

- Fi fọ́ọ̀mù àsọyé ẹlẹ́rọ kan tí ó wà ní ojú òpó ní **mdta.maryland.gov/ALB270TollSetting**; sọwọ́
- Sọ fọ́ọ̀mù àsọyé kalẹ̀ kí o sì fi èyí tí a kọ parí ráńṣẹ́ sí **ALB270TollSetting@mdta.maryland.gov**
- Tẹ̀ àsọyé sí ìwé kí o sì fi fọ́ọ̀mù àsọyé tí a kọ parí ráńṣẹ́ sí:
  **Phase 1 South: American Legion Bridge I-270 to I-370 Toll Rate Range Public Comment**
  **Maryland Transportation Authority**
  **2310 Broening Highway**
  **Baltimore, MD 21224**
- Pèsè ẹ̀rí nípa pípè wọlé ní **855-701-1977** kí o sì fi ohùn tí a gbà sílẹ̀ kansoso èyítí kò jú ìṣẹ́jú mẹ́ta lọ sílẹ̀

GBOGBO ÀSỌYÉ tí a gbà, bóyá ní ìgbẹ́jọ́ nípasẹ̀ ọ̀rọ̀ ẹ̀rí TÀBÍ nípasẹ̀ àwọn ọ̀nà mìíràn (fọ́ọ̀mù àsọyé, i-meeli, lẹ́tà, tàbí ohùn tí a fi ráńṣẹ́), ní a ó fún ní ÀGBÉYẸ̀WÒ KANNÁÀ. Àwọn àsọyé ni a gbọ́dọ̀ ti gba wọlé ni aago 5:00 ìrọ̀lẹ́ ní ọjọ́ kejìlá Oṣù Kejọ kí á lè gbe e yẹ̀wò fún àkọsílẹ̀ lábẹ́ àṣẹ.

*Bí o kò bá lè wọlé sí àwọn ohun-èlò lórí ayélujára, tàbí bí o bá nílò àkànṣe ìbùgbé lábẹ́ Òfin ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà tí ó ní Àléébù tàbí nílò àwọn iṣẹ́ ìtúmọ̀ èdè (ní ọ̀fẹ́), jọ̀wọ́ kàn sí Òṣìṣẹ́ ti MDTA ní Àkọlé VI ní mdtaeeo@mdta.maryland.gov tàbí ní 410-537-6720 ní ó kéré jù ọjọ́ mẹ́wàá ṣáájú ìgbẹ́jọ́ gbogbogbò náà.*